ADURA FA KUNMQ YO NILE AGANYIN

AWOGBA

omode fun Giri, Eyi, Hibu-ehin, Orere.
Ra Tire Ni Ile Egbogi
— ISE —
OLODUMARE
Ibadan ati Eko

ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

LADIES BRASSIERES

2/-6d, 3/- 4/-6d & 5/-6d each.

Obtainable at :-
A. B. AKINYEMI
10A, Moloney Bridge St.
LAGOS.

VOL. VII No. 439 LAGOS (SATURDAY) OJO ABAMETA OCTOBER 29, 1955 IYE OWO ELETI OFE KOBO MEJI (2)

Adura Fa Kunmo Yo Nile Aganyin

Irohin ti a gbo lati ileto kan ni igberiko ilu awon Aganyin ni wipe okunrin rogbodo kan ti o pe arare ni Ojise Olorun alaye ti o ma ngbadura fun awon enia wo abule oko kan lo ba awon agbe enia osise oko, to wa ni abule.

Nigbati baba aladura yi de ibẹ o lu agogo to ngbe dani lati pe enia jọ wa gbọ wasu rẹ, o si bẹrẹ si sọ ọrọ didun si wọn leti de'po ti awon ara Abule na bẹrẹ si da owo fun ati iṣu,ati agbado, wọn si fi aye fun lati ri ile wọ si.

Ṣe ẹnyin na mọ wipe "Mase ni ogun ma mọ" nigbati baba aladura yi fi idi mulẹ tan, ti o jẹ kumoyo tan, o bẹrẹ iṣẹ abuku rẹ ni ṣiṣe pẹlu awọn obinrin awọn to gba s'ọwọ sẹsẹ laipẹ lọ titi, aṣiri tu akara wa tu s'epo loja Ṣapọn, bi orin awọn ọmọ Eko.

Ni ọjọ kan ti bale rẹ lọ si oko, ni Baba aladura yi pe iyawo bale mọra, nibiti o ti ngbadura isalẹ lọwọ ni ọkọ obinrin wọle, enmọ! Kini eyi? a fi kunmọ ti ọkọ obinrin fa yọ ti o ki bọ agbadura-gba-tidi yi lara.

Jagun kigbe, ẹ gba mi o, ni ọpọ enia w'ọle, ki a ma d'enape'nu ọjọ na ni nwọn le baba aladura kuro ni Abule wọn.

ABỌ RE O.

LAGOS RACE CLUB

CLASSIFICATION NOTICE

It is notified for the information of Owners that in future a win at Ibadan races will be taken into consideration in any new classification made by the Lagos Race Club in the same way that a win at Zaria or Kano has always been taken notice of.

By Order,
of the Committee.

THE NATIONAL BANK
OF NIGERIA LIMITED

Ona tara ti enia legba lati di onisowo nile Nigeria wa ni ile ifowopamosi ti NATIONAL BANK
Enikeni ti o ba fe kan ogunlogo aimoye awon onisowo ile Nigeria lara, yala lati ma ta oja fun won ni, tabi lati ma ra awon ohun ogbin ile wa ki o lo si NATIONAL BANK

ILE ISE WA NI EKO:-
37, MARINA, P. O. BOX 508, LAGOS
AWON ASOJU WA NILU OBA NIYI
THE NATIONAL PROVINCIAL BANK
(Overseas Branch)
1. PRINCESS STREET LONDON E. C. 2.
THE COMPTOIR NATIONAL DESCOMPTE DE PARIS
8/13, KING WILLIAMS STREET, LONDON E. C. 4.

Alaiyeluwa Qba'binrin Ilu Oyinbo

Aworan inu Iwe wa yi ni eyiti Alaiyeluwa Ọba Obinrin ti ilu Oyinbo Gẹsi ya ni Edinburgh nigbati o lọ ba awọn Oloye nla pade. Oye ti a npe "Knights of the Thistle" Oye na jẹ eyiti Ọba James Keji da silẹ ninu ọdun 1687.

Ẹ wo Alaiye-Ọba na bi o ti nrẹnrin musẹ pẹlu aṣọ oye na ti o da b'ọrun lori aṣọ ti o wọ.

Laisi aniani, o da wa l'oju wipe gbogbo enia, t'ọkunrin t'obinrin, ni ọmọde ati ni agba ni yio ti ma fi oju s'ọna lati ganni Arẹwa Obinrin to ju obinrin lọ to mbọ wa bẹ ilu wa wo ninu ọdun ti ao bọ si ni nkan bi oṣu mẹta yi.

Adura wa niki Ọba Olodumare, Ọba Ọga-Ogo jẹki dide Alaiyeluwa na ṣ'oju ẹmi gbogbo wa.

Irohin aladun kan ti a gbọ ni wipe Ọba obinrin ti ilu Oyinbo Gẹsi yio dakan wa bẹ ilu Eko wa wo pẹlu Olufẹ rẹ ti a npe ni Duke of Edinburgh ninu oṣu January ti ọdun to mbọ yi.

Ọba'binrin Elizabeth Keji,yi ni yio jẹ akọkọ ọba ilu Oyinbo to wa si ilẹ wa mihin. Arẹmọ ọba ọkunrin ni ẹniti o wa si Naijiria wa yi ninu ọdun 1925, on ni a npe ni Prince of Wales to wa pada ni ọba Edward Kejọ.

Alaiyeluwa Ọba Obinrin ti a nwo aworan rẹ ninu iwe yi ni akọbi ọmọbinrin bibi inu Ọba Oninu're George Ẹkẹfa to w'aja ni ọjọ kẹfa oṣu February ọdun 1952. Ni ọjọ kejọ oṣu February kanna ni Elizabeth g'ori oye rọ'po baba rẹ, o si gb'Ade ni ọjọ keji Osu June, ọdun 1953.

A ki gbogbo ẹnyin ọkawe wa jake-jado Naij'ria wipe Ẹ ku af'oju s'ọna o.

ARADAN
A.P.C
POWDER

FOR
FEVER, HEAD-ACHE, RHEUMATISM NERVE & MUSCULAR PAINS.

EGBA TRADING ARADAN STORES
EBUTE METTA, LAGOS & BRANCHES.

ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS 28 Kosoko Street, Lagos P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAMS "ELETI-OFE LAGOS" Phone 23370

VOL VII NO. 439. LAGOS SATURDAY NOV. 29 1955.

A LE FI TULASI BA ENIA TUN ILE RẸ ṢE?

Gbolohun ibere oke wosika wa ọsẹ yi ni o wa si ọkan wa nigbati a fi oju inu wo ọrọ ile wiwo larin ilu Eko wa yi, ti awon Alaṣẹ ilu wa sọ di ijọgbọn si wa lọrun yi.

Otitọ ni ilu wa nfẹ titunṣe, ṣugbọn ki iṣe wipe ki a fi agbara mu enia jade ninu ile rẹ nitoripe a nfẹ tun ilu ṣe. Iba dara pupọ bi awọn alaṣẹ ilu wa ba le gba olukuluku awọn enia laye lati tun ile wọn kọ gẹgẹbi nwọn ba ti ni agbara mọ.

Bi awọn alaṣẹ wa ba gba ki ẹniti ile rẹ ba jẹ eyiti ko ba ibugbe enia mu, fi Pako (Board Building) kọ ile rẹ ti ko ba ni owo to lati fi mọ ni ogiri biriki, eniti o ba si ni agbara le kọ tirẹ ni pẹtẹsi.

Irufẹ imọran wa yi le mu irọrun wa pupọ lẹhinti awọn alaṣẹ ba ti yanju eyiti nwọn ma lo fun oju opopo - ọna (Roads) kuro tan, ju wipe ki a ko gbogbo awọn enia kuro, ki a tun ko wọn pada nigbati agbara wọn ko ni ka irufẹ ile ti awọn Alaṣẹ yio ṣe eto rẹ silẹ fun wọn lati kọ.

A fi eyi da imọran fun awọn Alaṣẹ ilu wa, ki nwọn gba yẹwo.

Jamba Moto Di Ona Ibadan Si Ilesha

Ibadan Gbogbo Oko ile ni ko ri ọna gba kọja lati busọ merindinlogoji si metadinlogoji ni ona Ibadan si ilu Ilesha lati ọjọ Ọsẹ to kọja nigbati awọn Moto ti di ọna pirapira.

Eyiti o kọkọ ṣe ni Mọto Akẹ'ru (P.W.D) kan ti o nlọ si Ifẹ kọlu Mọto Ak'ẹru (Lorry) kan to duro ni wọn bi ọpa aṣọ meji si Afara odo (K'ereni) Ọkọ P.W.D. na ju si ọwọ osi; o si lọ fi ori sọ igi Ọpẹ ni o ba ṣubu sinu omi, o wa tun yi oju si ọna Ibadan.

O pẹ diẹ, Ọkọ Akẹ'ru miran ti o tun fẹ kọja, ọkọ na jẹ ti Ọgbeni Aduroja ti ilu Ilesha, ni o tun wọlẹ, o si di ọna ni apa ọtun, nibẹ ni Ọkọ Ak'ẹru kan tunde ti o ko igi Gẹdu, eyi na tun yi ṣubu nibiti o ti nwa aye lati gba apa osi kọja.

Gbogbo ọna wa di pirapira, awọn Mọto miran ko le kọja mọ, ọrọ wa di ki nwọn ma fi ero parọ arawọn, awọn ero to nlọ si ọna Ilesha yio sọkalẹ rin lọ wọ Mọto Ilesha, awọn ero Ibadan ti o mbọ lati ọna Ilesha yio sokale rin wa wọ Mọto ti Ibadan.

BOOKS

Yoruba Uses of Psalms — 5/6
Yoruba Version 6th & 7th Bks. of Moses 15/-
Yoruba Key to Books of Moses - 20/-
Yoruba Secrets of Prayers 2/6
Fragrance Oil - 7/6

CONTACT :- Manager,
36, King George Avenue Yaba or
83, Idikan Street, Ibadan.

JZ.5631—OWO ORI/ORE MEJI ATATA) Tijani Alabi's (Sahara)
JZ.5632—SIKIRU AKINTUNDE/ALAFIN) Band

JZ.5668—IYERE/IBARIGHA) Theophilus Walokun's
JZ.5669—ITOJU EBI/KENEMA) (Ilaje) Band

JZ.5686—OMOGE/ONINU MEJI) Bashiru Alamutu's (Apala)
JZ.5687—ORISIRISI EWU/IRAGBEJE) Band

JZ.5707—OWO LESO AIYE/OLOWO AIYE)
JZ.5708—ITAN AKIYEYE/TOKUNRIN TOBINRIN) S. K. B. Ajao
JZ.5709—KALOWO KARASO/EJONIGBORO) Oru's (Apala) Band

JZ.5710—PATANI/AMALAGHA YEI) Ijaw Youths' Orchestra
JZ.5711—FRED AGUGU/NINETRY)

JZ.5712—TENIMASUNWON/ILU ALADUN) Seidu Sokoto
JZ.5713—IYAWO AREWA/JAGAJ GI) (Perente) Band

JZ.5727—ABAN JE/IDERA)
JZ.5755 - IGBEKELE/OWOLEGBON) Rosey Show Mambo Orchestra

"HIS MASTER'S VOICE"

Distributors THE UNITED AFRICA COMPANY LIMITED

* Obtainable from all the best stores

ABOKI

TI IWULO RE LOKIKI ylka Nigeria

KOSEMANI lo je fun ilekile Fun orisirisi AILERA, atata Gbogbonse lo je.

RA IGO KAN LONI nitori AJEBIDAN ni

LODO

I BUKUN - OLU MEDICINE STORES
Amunigun Street, Phone 189x, Box 295, Ibadan.

Eniti Ko Je Gbi, Ko Ni Ku Gbi

Awon baba wa su wipe Otito lo laiye, so otito ki o so ododo eniti o so otito ni Mole yio gbe. Ise ti Orunmila wa se pelu Ifa l'ode aiye ni, lati wa tun aiye se, bi o ti ntun ile aiye se to yi na, ko dun mo awon Irunmole elnu, ko si egbogi ti nwon ko se si Orunmila tan nitoripe, o nse ododo.

Nigbati o se gbogbo awon Irunmole dimolu wipe, awon ti be gbogbo Irunmole lowe si Orunmila, ko si, eniti o le da a, nisisiyi awon yio be Igba Mole lowe si Orunmila je eniti ko nfi Ifa re jafara, ni gbogbo wakati-wakati li o ndifa re wo lati wo o bi ewu ba nbo.

Li osen ojo kan bi Orunmila ti gbe Iporun re lule beni odu Ogbesa fu soju opon, o si bere si ki i bayi wipe:-

> Ina Awo Ojogbo, Orun Awo Ojogbo, Osupa Alatansere Ojogiri Awo Isalu Orun, Awon mererin lo nse ota Orunmila, Lojo ti nwon wipe, awon nlo ba Orunmila Lojo ti nwon wipe, awon nlo ba Orunmila jija kadi A ni ki o ru awo Iyan merin ati Awo obe meta Orunmila, gbo, o ru, O gbe-sa.

Nigbati oro yi di mimo fun Orunmila, o yara gun iyan awo merin ati awo obe meta, o gbe lo si ikorita li oju ona ti o wo ilu Ife.

Ina ti o siwaju mbo nile Orunmila o de ibi ebo yi, o gbe igba Iyan kan, ati awo obe kan, o si ya si egbe kan, o nje e lowo, beni Orun de, o gbe igba iyan kan, o ya si egbe kan Osupa de, o gbe tire, o ya si egbe kan o nje e. Sugbon nigbati Ojo giri de, o gbe igba iyan kan ti o ku' ko ri obe fi je.

Ojo giri awo Isalu Orun binu gidigidi si iru iwa ti awon elegbe re hu si yi, o si nlepa won lo, o ba Orun Awo Ojogbo loju ona, o lu pa, o ba Ina awo Ojogbo, o lu pa, o si ba Osupa Alatansere o lu pa, on papa si binu pada lo si Isalu Orun. Bayi ni ote ti nwon di si Orunmila wole.

Awon Babalawo gbogbo wipe, ese Ifa yi Ogbe-sa nfi han ni bi o ti je wipe awon Irunmole ko le ridi Orunmila, nitoripe o ga ju gbogbo won lo, Esu Elegbara papa a mo o ti.

> Awon Akere-sohun, Awon Adagba sohun,
> Awon lo difa fun Orunmila, lojo ti iku kan ile re lati wa, Ti gbogbo awon Oloja-loja, ati awon Erinkin-rinkin yio mo oruko awon Odun ti iku yio si ma pa won, Orunmila da Iporun re, kini on yio se ki iku mase le, pa on (Ajakale Arun) A ni Sigidi kan ti a fi egusi

Se ehin re ni ebo, ki a gbe si ikorita meta, Idigbe Itan bi edu Ifa yi ti je, igba miran. Sugbon odu Ifa yi ni Odun Ifa, Odun Oro, Odun Isu. Odun Egungun; Odun Agemo, Odun Orisa Oko, Odun Orisa Idi, Odun Sango, Odun Obatala, ati Odun Orisa Ogiyan. Eniti ko ba se oro odun tire nse ni odun na ma npa won. Sugbon a se oro odun tabi a ko se oro odun, ko si eyiti o le pa Orunmila, beniko si niti o le ridi re.

Irohin Ilu Oyinbo

AWON OMO OGUN ILE GESI KA'SE NILE NI KHARTOUM

Ni owuro ojo kan ni ose ti o koja, oko oju irin gigun kan, ti eruku ti bo bitakun, ko awon isowo omo ogun ile Gesi ti won wa ninu egbe kiri kuro ni Khartoum lo si etikun Sudan. Awon omo egbe ologun yi ni a npe ni 'Royal Leicester Regiment;' ni etikun Sudan ni won yio si ti ba oko oju omi ti a npe ni "H.M.T. Charitun Star" lo si ile Cyprus. Awon omo ogun ile Egypt papa ti mu ona Wadi Haifa pon. Irin ajo won yio si pari nigbati won ba de Cairo ti se olu ile Egypt.

Eto yi je okan ninu igbese awon ara Sudan lati ma se eto Ijoba ara won; ki a si to ri ose melo kan si gbogbo awon omo ogun ajeji ni yio ti tuka nibe.

Ki awon omo gun ti egbe Leicester to lo opolopo eiye, Idaraya, ati duniyan ni won fi tuka, Ayo yi wa pinmlarin nigbati won fi ago won ti apa isale le awon omo ogun ti o adaboboile Sudan lowo. Pelu ilu ni won fi dagbere fun Gomina gbogbogbo ti Sudan olola Knox Helm nigbati nwon fe te oko irin leti.

Ki a to ri osu kan si nisisiyi ewe, awon omo egbe ogun ti ofurufu ti nwon ti wa pelu Ijoba Ile Sudan bi odun Mejilelogun sehin yio kuro bakanna

EMMANUEL LADIPO RI OHUN ISIRI

Ohun ti o je ohun isiri pupo ju fun Emanuel Ladipo ni London ni inurere awon enia ati opolopo ere ti o wa yika ilu na. Emmanuel ti se omo odun medogbon nisisiyi sese de ilu Oyinbo ni lati lo ko nipa ise agbe sise ni ile eko ti Wiltshire. Odun meta pere ni yio fi pari eko re. Bi o ba si ti pari gbogbo eko na patapata a ni ero wipe yio pada wa sise ni abe Ijoba Nigeria tabi ni abe igbimo ti a npe ni "Production Development Board". Emmanuel je okan ninu awon ti Ijoba Ipinle Iwo-Orun Nigeria ran lo lati lo ko eko; baba re si je okan ninu awon igbimo egbe ibile ni Ogbomosho.

Olori Ilewe Eko Ede Arabic Ni Kano

Ogbeni Sheik Awad, ti se olori nibiti won ti nko ede Arabic ni Kano ni apa oke odo-oya ni Nigeria ti lo lo osu kan ni ile Gesi lati lo ko awon ona ti won ngba se eto Eko won. Ogbeni Awad ti o ti se adajo ri ni Sudan tun de Ile iwe St. Albans ninu ajo ibewo re yi. Lehinna o lo si opolopo ilu ti o ni okiki nipa eko, o si lo wo awon ile eko giga Cambridge. Oxford ati Edingburgh. Ni St. Alban o lo wo eniti se baba igbakeji olori ile-eko re ni Kano ti a npe ni ogbeni W. R. Hiskett.

LE IGESI GBON'WO SI KEKE ATI IRIN

Nigbati awon igbimo onisowo ile Gesi se iwadi ati ayewo, won ri i wipe o to egberun din meta osuwon ti awon ohun elo irin ti won fi ranse lodun yi fi tayo ti odun ti o koja.

Ninu eyi ni a ri oko ayokele bi egba din ni ogofa ati ogofa lelegberun oko akeru, Keke ti won fi sowo si Nigeria le legbarun lona mewa, eyi si fi egberun din okanleladota ju ti odun ti o koja lo.

Omoba Margaret Se Iranlowo Owo

Omo oba Margaret tiise aburo oba obinrin ile Gesi ati omo oba Alice pelu oloye ti Athlone ti fi igba poun ran awon ti iji nla baja ni British West Indies lowo, Agbajo egbe awon osugbo ra ti fi bi odunrun poun miran lele fun awon omo egbe won miran ti o wa ni Barbadoes, Greneda ati Honduras ti o wa labe asia Gesi gegebi iranwo. Olu akowe ile Gesi ogbeni Lennox-Boyd si o ko se ifile iranlowo owo yi ninu ero gbohun-gbohun ni ile Gesi, nisisiyi won si ti ri to egberun lona marun-dilogoji poun.

Owo ti o tobi ju ti won ti i ri gba lati odo enikan ni egbedogbon Poun, eyiti o si kere ju ni kobo mejo ti agbalagba kan fi ranse, Enikan ti o tun fi sile marun ranse ko iwe ti lati fi han iru oyaya ati ife ti awon ti iji nla yi ba ja ni si omo oba Margaret nigbati o rin irin ajo ibewo lo sibe. Eyi si fi han iru ona ti awon owo kekeke ati nlanla ngba wole fun iranlowo yi

Aseyi Samodun o, Ijo Omupo.

Irohin ko to afojuba ni ni owuro ojo keji osu yi ti awon Ijo St. Michael Anglican Church, Omupo (Eka Eko) se Ajodun Ketinlelogun ti Isin Ikore ni Ile Eko No. 68, Apongbon Street, Lagos. Isin Ikore na bere pelu orin aladun lati odo Egbe Akorin Ikore. Orin na dun tobe ge ti o fi jepe enitl ko mo jo, o nmi; o si fun enikeni ti o je alejo ni isiri lopolopo. Ogbeni J. Ade Jones ni o wasu.

Ni ojo keji re ti won ta oja Ikore (Bazaar) enia ti o wa to egba meji lokunrin ati lobinrin, awon gbajumo, ti o si Oja Ikore pelu opolopo owo lowo ni :- Joel Amoo, Timothy Ige, Joseph Akano ati awon Iya afin, Onibipe Arike, Sariah Asabi, Comfort Moromoke. Ogbeni S. A. Omoyiola ni Alaga Igbimo Ikore, awon ogbeni J. A. Adebara ati E. A. Mustapha ni akowe,

A dupe lopolopo lowo awon Ijo wa bi Baptist Ajase'po, Igbaja, Okeyapo, Idofiban, Iludun, Esie, Igb'owu, ati opolopo awon miran. Olorun ko fi opolopo odun bayi se oju wa pelu ohun rere Amin.

ASEYI SAMODUN O

Iyawo Tori Sile Mesan Gb'ogbe

WARRI:- Okunrin kan ti oruko re nje John Dee onise Roba ni a gbo wipe o sa iyawo re, Alice, l'ogbe lori nitori owo sile mesan (9/-).

Bi oro na ti lo niyi:- a gbo wipe okunrin na so fun Adajo ni Kotu ilu Warri wipe on fun iyawo on ni owo sile mejila (12/-) pamo, nigbati on bere owo na lowo iyawo on, sile meta pere l'o ri mu jade.

Nitori eyi ni o se fe kuku pa iyawo na ki on si pa ara on pelu. Adajo ni ki o lo fi ewon osu merin bu omi suru mu.

A gbo pe Dee sa iyawo re l'ogbe lori, o tun sa meji ninu awon ebi re.

Awon Olugbe Ije Koiti Ni Kuro

A gbo wipe koi ti to asiko ti Ijoba yio gba iiu Ije l'agbegbe Qbalende gegebi ati gbo ri. Qro na koiti ni iforiti wipe asiko bayi ni nwon yio lo ile ibe.

Beni awon opolopo enia ni a gbo wipe won ti ko kuro ni Ije lo si Apapa, Mushin ati Ibomiran lo so arawon ljo si, nigbati Ikede akoko ti jade ninu awon iwe Irohin ni iberu ki nwon ma ba da won siasia nigbati awon Alase ti ko lati wa aye miran fun won.

NOW AVAILABLE
BULES, BADSTA ADS
PAINTS DISTEMPERS,
SAFES Etc.
Just Write, Call, Or
Phone 21372
IKORODU TRADING COMPANY
20/28 Balogun Street,
(P. O. Box 395) Lagos
AND
NEW COURT ROAD
IBADAN

Kere o!

A ti ni orisirisi ogun Germany to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ko to tan.
J. A. AJAO BROTHERS
Medicine Store
7. Egerton Road, Lagos

Wompari Enia Wo Itimole

IBADAN — Awon Qlopa so wipe lati ojo ti owo ti te Johnson Oyedele jogbon, ni ilu ti ro wo p fun iyanu ole.

Oyedele yi fi Ekotedo se ile isapamo re, o si je Ogbo'le enia larin ilu-lori eru Alagba Oyinbo John Verity ti nwon ji ni Qlapa mu jaguo ewele na fun u, O si di bi emefa ti nwon nja'le to je wipe On ni won mba nidi re.

Beni awon wa oro itewo kan ti nwon do ile Oyedele ijogbon l'Ekotedo, nibe ni nwon ti ri eru ajoji - Ako ninu ole ni Oyedele ise.

Egbogi Ti Colgate Ti A Fi Nfo Ehin Nikansoso Lo Daju Ti O Si Nmu Ireti Wa Fun Opo Enia

LOSAN ATI LORU KO NJE KI EHIN ENIA BAJE

Lilo ti opo enia nlo egbogi yi fihan wipe egbogi yi ko njeki ehin enia baje pelu egbogi Gardol.

Awon Alase isegun ehin ti se ayewo re fun odun kan pe egbogi na ko nkuro beni ki nsa. Bi o ba sa ti nlo ni ojojumo, laro ati ni ale, ko ni jeki ehin baje l'osan t'oru.

Sodium N. Lauroyi, Sarcosinate

SAME RAMILIAR, PACKAGE

OKAN NINU AWON OJOGBON ONISEGUN EHIN TI SE AYEWO ORO YI.

A ti fi Ododo oro yi han ninu iwe ti awon Onisegun hin te, nwon si ti gba wipe egbogi ehin ti Colgate pelu Gardol je eyiti o dara fun ehin lo baje ju egbogi miran lo. Nitoripe egbogi Gardol ki njeki ehin baje, lo se jeki awon alase gba wipe egbogi Colgate ati Gardol lo dara julo

Ko si egbogi ehin kan ti o dara bi eyi.
Ko ni jeki enu re run
Ko si ni jeki ehin re baje,

O Dara T'osan T'oru Ko Njeki Ehin Enia Baje.

IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.

A ma je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode

OMORELA BABY MIXTURE

(SILE MEJI ABO 4/6d. FUN IGO KAN)

O wa lodo :—
COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS

Iforuko Sile Fun Idibo Ti Ọdun 1955 Ni Iwo-Orun

Bawo Ni Ao Ti Fi Oruko Sile

A. Eniti O Ni Eto

Lati asiko yi lọ, gbogbo enia ti o je olugbe ilu-kilu ni apa Iwọ-Orun le foruko silẹ ni ilu rẹ. Ninu oṣu Nofẹmba, gbogbo ọkunrin ati obinrin ti o ba to ọmọ ọdun mọkanlelogun tabi tojubẹ lọ, ti o si jẹ ọmọ ilu ti o fẹ f'orukọ silẹ fun Idibo, ki o lọ gba iwe if'orukọ silẹ ti a npe ni FORM A. yio si kọ orukọ rẹ ati gbogbo eto pe pere-pere sinu Iwe na. Wọn le ri Iwe If'orukọ silẹ FORM A. gba ni Ile-iṣẹ if'orukọ silẹ ti tosi wọn. Wọn si ni lati da Iwe if'o-rukọ silẹ na pada sile iṣẹ if'orukọ silẹ funrawọn. Bi ẹ ba ti kọ gbogbo rẹ daradara sinu Iwe if'orukọ silẹ, ẹni lati fi orukọ meji tabi jubẹlọ ati ibugbe yin si, Oluranlọwọ Ọga Ile-iṣẹ If'orukọ silẹ yio si gba a. Ẹniti o ba ngbe ilu rẹ, a ko ni ki o mu Iwe-owo-ori tabi ti owo-ode kankan wa.

Ẹnikẹni to ba jẹ ara ilu ti o si nsan Owo-ori tabi Owo-Ode, (ako sọ ti owo-omi tabi ti Ina Oni-mọnamọna) ni ilu na, ṣugbọn bi o koiti to ọmọ ọdun mọkanlelogun o le f'orukọ silẹ fun idibo, ibaṣe ọkun-rin tabi obinrin, ninu oṣu Nofẹmba, niwọn igbati ẹnibẹ bati mu Iwe - ẹri to fi san'wo ni ọdun 1954 si 1955, ti awọn alaṣẹ agb'owo ṣe fun u.

Eto ti awọn ti ki ise ara ilu yato. Ki a kọkọ ranti wipe awọn ẹnibẹ ni ẹtọ if'orukọ silẹ fun idibo ti ilu wọn. Bi nwọn ko ba fẹ lo ẹtọ yẹn, ti nwọn si f'orukọ silẹ fun idibo nilu ti ki ise ilu wọn, wọn ni-lati ṣe eto isalẹ wọnyi:-

(a) Ẹniti ki iṣe ara ilu ti o fẹ dibo yi, (Iyẹn ni wipe, nwọn ko bi on tabi baba rẹ ni ilu na) O nilati jẹ ẹniti o ti ngbe ilu na fun ọdun meji ni ibẹrẹ oṣu Nofẹmba, 1955.

ati

(b) wipe o nilati ti san'wo ori tabi owo-ode ti Ijọ-ba Ibilẹ, (a ko sọ ti owo-omi tabi ti Ina Mọ-namọna) fun Alaṣẹ ilu na fun ọdun meji gbako, ọdun 1953—54 ati 1954—55.

O jẹ ohun pataki pe ki olukuluku enia mọ amọ-ye nipa awọn enia mejeji ti a wi yi. Iwe ofin sọ wipe ẹnikẹni ti o ba jẹ ara ilu ni Iwọ-Orun le fi orukọ silẹ fun idibo nilu rẹ Ẹniti ki iṣe ara ilu ati ara ilu ti o ba fẹ f'orukọ silẹ fun idibo ni ilu mi-ran le ṣebẹ lori owo-ori tabi owo-ode ti o ti san.

Ọpọlọpọ enia ni yio lọ f'orukọ silẹ fun Idibo ni Iwọ-Orun ninu oṣu ti o mbọ lai ni iyọnu owo-Ori tabi Owo-ode. Ki t'ọkunrin t'obinrin maṣe jẹki gbogbo ọrọ isọkusọ nipa Iwe-ẹri Owo-Ori tabi ti Owo-Ode da wọn l'ọkan ru. Ẹ mu Iwe If'orukọ silẹ yin ti ẹ ti kọ daradara lọ si Ile-Iṣẹ If'orukọ silẹ ti o wa nitosi yin, niwọn igbati o ba ti jẹ ara ilu na ni nyin, ao gba a, ao si fun yin ni Iwe-ẹri, Olukuluku enia si ni lati tọju awọn Iwe-ẹri tirẹ daradara.

NIBO NI AO TI FI ORUKO SILE

Ni gbogbo ilu Iwọ-Orun yika ni a ti da Ile-iṣẹ Ifo'rukọ silẹ si nisisiyi. A ni ireti wipe yio le ni ẹgbaata Ile-iṣẹ If'orukọ silẹ ti ao ti pese silẹ ni ọjọ kini oṣu Nofẹmba ti ao bẹrẹ si ma gba awọn enia lati f'orukọ silẹ. L'oju ode Ile-iṣẹ Ifo'rukọ silẹ kọkan ni ao i Iwe Ami nla (Poster) si. Ninu Iwe Ami nla yi ni ẹ o ti ri Apoti-Ibo ti a fi tadawa rusurusu ya. Apoti-ibo yi jẹ eyiti a yan ti ao lo ni gbogbo ilu Iwọ-Orun gẹgẹbi Ami ti yio fi awọn Ile-Iṣẹ If'orukọ silẹ fun idibo han. Ninu oṣu Nofẹmba nibikibi ati nigbakugba ti ẹ ba ri ile ti o ni Ami Apoti-idibo ti a ya lara ogiri rẹ l'ode ki ẹti mọ wipe Ile-iṣẹ Ifo'rukọ silẹ niyẹn. Ọpọlọpọ Ilewe ni ao fi ṣe Ile-iṣẹ If'orukọ silẹ. Ao tun fi Iwe Akiyesi nla si gbogbo Ile Igbimọ Ibilẹ ti yio fi orukọ oriṣiriṣi awọn adugbo ti Ile-iṣẹ if'orukọ silẹ wa han. Ni ọjọ - kọjọ, ayafi ọjọ ọsẹ (Sunday) lati ọjọ kini oṣu Nofẹmba to fi de ọgbọn'jọ ni ẹ le lọ sile Iforukọ silẹ to sunmọ yin. ki ẹ si pari gbogbo eto ifo-rukọ silẹ yin. Ile - iṣẹ If'orukọ silẹ yio ma ṣi silẹ ni wa-kati meji - meji l'ojojumọ ni ọsan. Awọn Ile - iṣe na yio ma ṣi silẹ fun awọn enia lati agogo mẹta - abọ di marun abọ irọlẹ. A o fi Iwe Akiyesi si Adugbo yin ti yio sọ igbati Ile - iṣẹ If'orukọ silẹ yio ṣi silẹ. Bi o ba fẹ gba Iwe If'orukọ sile ti a npe ni Form A. ki o lọ si Ile - iṣẹ If'orukọ silẹ to mbẹ nitosi rẹ, ki o si bere lọwọ Ọga to wa nibẹ ki o fun ọ ni ọkan. yio si fi fun ọ. Ẹ le kọ orukọ yin sinu Iwe Iforukọ silẹ, ti ẹ gba tabi kiẹ kọ sinu ẹda re ti o wa lẹhin Iwe ti a ṣe ti a npe ni "Ẹ Fi Orukọ Sinu Iwe Adibo Ni Oṣu NOFEMBA" 1955. Tabi ẹ le lo eyiti nwọn ba tẹ lati ọwọ ẹgbẹ Oṣelu. Niwọn igbati eyiti ẹ ba lo ba ti ba eyiti Ijọba Iwọ-Orun ṣe ni apa keji iwe ofin If'orukọ silẹ fun idibo 1955, mu ao gbaa.

BAWO NI AO TI SE KO IWE IF'ORUKO SILE (FORM A)

Nigbati o ba ti gba Iwe If'orukọ silẹ O le kọ funra rẹ tabi ki o bẹ ọrẹ rẹ ki o ba ọ kọ, tabi ki Akọwe ẹgbẹ Oṣelu rẹ ba ọ kọ tabi ki o lọ si ile iṣẹ If'orukọ silẹ ki o bẹ Oluran-lọwọ Ọga Ile-iṣẹ If'orukọ silẹ ki o ba ọ kọ.

Ẹ le kọ Iwe If'orukọ silẹ nibẹ tabi nibomiran, gẹgẹbi ẹniti o fẹ f'orukọ silẹ ba ti fẹ. Ẹniti o fi orukọ silẹ nilati fi ọwọ ararẹ kọ tabi ki ofi ika godogbo tẹ iwe, o si nilati fi ọwọ ararẹ mu lọ sile-iṣẹ if'orukọ silẹ ti o sunmọ ile rẹ. Bi o ba fi ran enia, tabi o posu rẹ tabi fi o ran ọrẹ rẹ tabi oniṣẹ-ẹgbẹ oselu rẹ, a ko ni gba. Olukuluku enia nilati fi ọwọ ararẹ mu iwe tirẹ lọ si ile-iṣẹ If'orukọ silẹ funrawọn-

Nigbati ẹ o ba kọ iwe if'orukọ silẹ yin ẹ ṣe ranti nkan wọnyi:- Ni ila kini, kọ orukọ Ile-iṣẹ If'orukọ silẹ to mbẹ nitosi rẹ. Ni ila keji o nilati ko orukọ rẹ si ni akotan. Orukọ ti a ko ba pere-pere a ko le gba. Onilati kọ orukọ meji silẹ bi ko ba ju bẹ lọ Orukọ abisọ ati orukọ ti ẹsin rẹ ati orukọ baba rẹ tabi ti obi rẹ. Onilati kọ ki o han gedegbe fi orukọ abisọ tabi ti obi tabi ti ẹsin gbẹhin. ṣakiyesi, bi orukọ enia ba njẹ Salami ati Ojo, O nilati fi eyiti o jẹ abisọ tabi ti obi rẹ han. Oluranlọwọ Ọga Ile-Iṣẹ If'orukọ silẹ yio fẹ mọ ewo ni orukọ obi oluwarẹ bi Ọgbẹni Salami ni tabi Ojo. Bakanna ni o jẹ pataki ni ila kẹta Iwe If'orukọ silẹ (FORM A) pe ki o kọ oru-kọ adugbo rẹ. Ki o kọ Nọmba ile rẹ ati opopo-ọna ibiti o ti fi orukọ silẹ bi o ba ṣeṣe.

Bi nwọn ko ba Nọmba ile ni ilu ti o ngbe ti ko si si orukọ titi nibẹ, o nilati kọ Orukọ Agbole tabi ti Adugbo ti o ngbe silẹ. Bi o ba f'orukọ silẹ ninu ile Igbimọ Ibilẹ nitoripe nibẹ ni nwọn bi baba rẹ tabi iwọ paapaa, oni lati sọ orukọ ile yin nibẹ. Bi o ko ba kọ gbogbo eto na daradara sinu ila kẹta ti Iwe if'orukọ silẹ (Form A) yio ṣoro fun ọ lati ri orukọ rẹ ninu iwe ifi orukọ han ti adugbo rẹ ni oṣu January nigbati ẹ ba nyẹwo. Nigbati o ba nkọ ila karun ninu

(Wo yoku l'oju ewe kẹfa)

(O bere l'oju ewe karun)

Iwe I'oruko silẹ o nilati kọ o ukọ ti a npe ile Igbimọ Ibilẹ ti o wa ayafi bi o ba jẹ pe ibi ti o fẹ f'oruko siịẹ fun kọ ni o ngbe, o si ni'ati kọ oruko adugbo ti nwọn bi ọ tabi baba re. Oruko ti a npe Ile Igbimọ Ibilẹ wa ninu Iwe ti a fi da Igbimọ na silẹ. Ninu gbogbo rẹ, akọkọ ninu Iwe iforuko silẹ ti a ṣe ni "A" bayi, ọpọlọpọ enia ni yio yọ ọrọ ti a kọ bayi kuro "British Subject" Ninu gbogbo rẹ, awọn to jẹ pe ilu wọn ni nwọn f'oruko sile yio yọ idaji kuro ninu ọrọ ti kọ "B", bayi si, eo si kọ gbogbo idaji yoku. Lọna keji ẹwẹ, enit' ki iba se ọmọ ilu ti o f'oruko sile nilati kọ ọrọ ti iṣiwaju ki o si yọ idaji to ku kuro. Gbogbo enito ba ni ẹtọ lati f'oruko silẹ lori owo-Ori tabi Owo-Ode ni lati mu iwe-eri to fi san'wo wa fun aiyewo Oluranlọwọ Ọga Ile-iṣẹ Iforukọ silẹ. Nigbati nwọn ba mu Iwe Iforuko silẹ wọn lọ sile iṣẹ iforuko silẹ. Ki ẹ ranti pe enikeni to ba foruko sile nilu re ko ni lati mu iwe eri owo-kowo kan wa.

Oluranwọ ọga ti o nfi orukọ silẹ ti o mbẹ ni ile IF'orukọ silẹ kọkan, yio kọ gbogbo ohun ti o ba fẹ sinu iwe Kadi ti yio si da pada fun ẹniti o mu iwe wa, iyẹn ni wipe oluwa rẹ gba Form A. Oluwa rẹ ni lati ṣọra wipe ki o to jade kuro ninu ile ti o ti forukọ silẹ, ki o ri daju daradara pe, nwọn fun on ni iwe kadi miran. Nitoripe ohun pataki ni iwe na jẹ fun Oluwa rẹ. Ko nse lati fihan nikan wipe, o ti tọwọ bọ iwe Form A lati fi orukọ rẹ silẹ gẹgẹbi ẹniti o lẹtọ lati dibo, ṣugbọn bi o ba di ọdun 1956, iwọ yio tun ni anfani lati lo iwe na eyi ni yio si jẹ ẹri wipe o ti lọ forukọ sile, bi o ba tile jẹ wipe orukọ rẹ ko si ninu iwe akọkọ ti a ti fi ndibo tẹlẹ ri. Bi a ba ti fi orukọ rẹ silẹ tan ti a si ti tẹ ẹ jade, ohun ti o dara ni ki o ṣe akiyesi Nọmba ti a fun ọ ninu eto orukọ na, ki o si kọ nọmba na si ẹhin iwe Kadi ti a fun ọ. Bi o ba ti le ṣe eyi, iwọ yio ri wipe irọrun ni yio jẹ fun ọ nigba gbogbo ti a ba nfẹ dibo yan enia si igbimọ ni apa Iwọ Orun tabi ti Igbimọ agbegbe kọkan ti a ba fẹ lati ṣe. Irọrun ni yio jẹ fun ọ lati dibo nigbati o ba ti yọ iwe Kadi nibi idibo. Awọn ọrọ ti a ba kọ silẹ yio jẹ iranlọwọ fun awọn akọwe lati tete wa orukọ rẹ ri.

GBIGBA TABI KIKỌ

Nigbati o ba di ọjọ kini oṣu January ọdun to mbọ iwọ yio ri awọn orukọ ti a fi patẹ kakiri si bi awọn ile ti a nfẹ dibo, ninu rẹ ni, a ti kọ orukọ awọn ti o ni ẹtọ ti a si ti forukọ rẹ silẹ lati dibo ni agbegbe kọkan. Iwe na yio wa fun ayẹwo ẹnikẹni fun odidi ọjọ mẹdogun. Ẹda iwe na yio si wa fun tita fun enikẹni. Ohun ti o dara ni wipe, ki o ṣe ayẹwo iwe na lati wo, bi a ba kọ pe daradara, boya a le ṣi orukọ elomiran kọ, tabi boya ko nṣe ile ibẹ ni o ngbe, boya ẹwẹ, a ti gbagbe lati kọ orukọ oluwa rẹ. Fun odidi ọsẹ meji ninu oṣu January, 1956 ni iwọ yio fi ni anfani lati ṣe ayẹwo iwe na. Bi ohun kan ba si yingin ninu rẹ, iwọ yio tete ni anfani larin ọjọ kini de ọjọ kedogun oṣu January, 1956 lati sọ fun awọn Olotu idibo wipe aṣiṣe ni eyi o.

Iwe ti a fi ngba ati kikọ, a le ri gba ni ile iṣẹ ibiti a ti nforukọ sile. Lẹhin ti a ba si ti kọ gbogbo ohun ti a fẹ sinu iwe na tan, ao mu lọ si ile iṣe ibiti nwọn ndibo. O yẹ ki a mọ eyi ni pataki bi bẹkọ, iwe ti oluware kọ, yio bọ s'ofo, bi a ko ba tete ri gba ki o to to opin ọjọ 15th oṣu Jan., 1956.

Lati ọjọ kerindinlogun oṣu January ti ọdun to mbọ ni Ọga Ile-Iṣẹ Il'oruko silẹ yio bẹrẹ si gbọ gbogbo awọn ọrọ kikọ ati gbigba (Claims & objection) ti awọn enia ba mu wa lati gbogbo ile idibo bi ọgọrin to mbẹ nile Iwọ-Orun. Bi a ba si ti pari gbogbo rẹ, ni ao fi iwe ti orukọ gbogbo enia to foruko silẹ fun idibo wa ranṣẹ, emi yio tẹ wọn sinu Iwe.

P. H. BALMER
OLOTU—IDIBO

IBADAN, 24th October, 1955.

R.S.P.C.A. Holds Animal Welfare Week

The annual welfare week of the R.S.P.C.A. started yesterday, Thursday October, 27, and will continue till November, 5, 1955.

Among events listed in the programme are :- Radio talks, Lectures and Cinema Show.

Ọdun Nobiyu Lawal

Ni alẹ ọjọ Alamisi mọju Jimọ ni awọn jọnmọ Musulumi ṣe aisun ajọdun ọjọ ibi Aṣiwaju Ẹda, Anọbi Muhammed.

A fi eyi ki enyin ọmọ iya wa musulumi jake jado Naijiria, Ẹ ku Ọdun ẹ si ku iyedun aṣeyi ṣ'amọdun o.

Irora Orikerike

Boya Kidinrin le fa a

Ise Kidinrin ni lati mu awon idoti ti o mbe ninu eje ara kuro nigbati ko ba sise dara-dara idoti na awojo po sibikan, eyi lo njeki awon orike bere si dun ni.

Ohun ti a le fi wosan ni wipe ka se iranlowo fun Kidinrin naki o le sise rere. Egbogi De Witt na kakiri aiye ni a si nta egbogi na a a Opo ninu iwe ni a ti ri gba lati odo orisirisi enia ti awon naa ri ise ti De Witts se fun awon. Danwo lora okan ni sobu egbogi.

Ohun ti o nfa nigbati Kidinrin ko ba sise tara, sugbon bi enia ba ti lo egbogi yi alafia yio desi oluwa re, nitoripe ara Kidinrin ni yio ti sise. Danwo lo ra ni sobu egbogi.

DE WITT'S PILLS
for Kidney and Bladder Troubles

REMEMBRANCE DAY
SUNDAY, 6TH NOVEMBER, 1955.

A Service will be held in the Cathedral Church of Christ on Sunday the 6th of November at 10. 30 a. m.

2. The General Officer Commanding, Nigeria District, will arrive at the west door of the Cathedral at 10. 25. a. m. and will be met by the Provost.

3. His Honour the Governor-General's Deputy will arrive at the west door of the Cathedral at 10. 28 a. m., where he will be met by the Bishop of Lagos.

4. A certain number of the seats will be reserved for which tickets will be issued. The remaining seats in the Cathedral will be available to the public.

5. Copies of the Order of Service will be distributed at the Cathedral.

6.Persons attending the Service should be in their seats by 10. 20 a. m. Uniform will be worn by those entitled to do so.

7. At 10. 55 a. m. a Guard of Honour from the 2nd Battalion, Nigeria Regiment, will be mounted at the War Memorial, Idumota.

8. At 11 a. m. two guns will be fired. All noise should then cease until two minutes after the hour when one gun will be fired. In the Cathedral, buglers of the Nigeria Police will sound the Last Post and the Reveille immediately after the silence.

9. At the close of the Service, His Honour the Governor-General's Deputy, followed by the General Officer Commanding, Nigeria District, and the Secretary of the Nigerian Ex-Servicemen's Welfare Association, will leave the Cathedral by the West door and will drive to War Memorial by way of the Marina, Balogun and Ereko Streets. On arrival at approximately 11. 20 a.m. they will be met by the Acting Chief Administrative Officer Lagos. wreaths will be laid by -

His Honour the Governor-General's Deputy.
The General Officer Commanding, Nigeria District.
The Acting Chief Administrative Officer, Lagos.
The President of The Lagos Town Council.
The Secretary of the Nigerian Ex-Servicemen's Welfare Association.

10. His Honour the Governor-General's Deputy will leave by way of Victoria Street and Tinubu Square.

11 The Cathedral Service will be broadcast by the Nigerian Broadcasting Service

12. The War Memorial will be flood-lit on the nights of the 5th and 6th of November.

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kokoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23370